# IPARUN SODOMU ATI GOMORRA

### Gẹnẹsisi 18:20-23; 19:1-29

### ẸKỌ 10 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni ìye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa" (Romu 6:23).**

**A Dá Ẹṣẹ Lẹjọ**

Ọlọrun jẹ Ọlọrun mimọ́, O si da eniyan lati jẹ mimọ́, O ṣe aye ni mimọ́ ati didara, igbadun si wa ninu aye.

Ṣugbọn ẹṣẹ fa ibanujẹ wa. Ẹṣẹ mu aisan pẹlu ọpọlọpọ oṣi wa. Ẹda eniyan di ibajẹ́. Lati igba iṣubu Adamu, iwa ibajẹ ẹda ti fara han. Ọmọde kekere paapaa a maa fi ami ibinu han; bi eniyan si ti n dagba si i bẹẹ ni o n fi iwa ẹṣẹ ẹda rẹ han siwaju bi oun ko ba fi ọkan rẹ fun Jesu. Ṣugbọn Ọlọrun korira ẹṣẹ.

Lati igba de igba ni Ọlọrun ran idajọ sori Israẹli nigba ti wọn dẹṣẹ. Olukuluku ẹṣẹ ti a ti dá, ti a ko ba ronupiwada rẹ ni yoo fa idalẹbi pẹlu ijiya lile wa. "Oluwa mọ̀ bi a ti iyọ awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun kuro ninu idanwo, ati bi ã ti ipa awọn alaiṣõtọ ti a njẹ niya mọ de ọjọ idajọ" (2 Peteru 2:9).

**Awọn Ẹṣẹ Sodomu**

Ẹṣẹ Sodomu oun Gomorra buru jai. Wọn bẹrẹ pẹlu "irera, onjẹ ajẹyo, ati ọpọlọpọ oraye, … bẽni on kò mu ọwọ talaka ati alaini lokun" (Esekiẹli 16:49). Boya loju wa iwọnyi ko jọ ẹṣẹ ti o buru ju, ṣugbọn wọn a maa sin ni lọ sinu iwa buburu ti o ju bẹẹ lọ. Ọwọ ti o ba dilẹ, a maa bọ sinu wahala. Ọlọrun n fẹ ki awọn ọmọ Rẹ̀ fi tinutinu sin Oun, ki wọn ma si fi akoko wọn ṣofo. Eṣu le ṣiṣẹ laarin awọn ti wọn jẹ alajẹki ati awọn ti o gberaga to bẹẹ ti wọn ko ni i fẹ tẹti silẹ fun imọran rere. Awọn ti wọn ba gberaga a maa jẹ amọ-ti-ara-ẹni-nikan pẹlu, wọn ko si n ni ọkan lati ṣe iranwọ fun awọn ti n fẹ iranwọ. Awọn ẹṣẹ Sodomu wọnyi yọri si ẹṣẹ miiran; Ọlọrun si sọ nipa awọn eniyan naa pe, "Nwọn si gberaga, nwọn si ṣe ohun irira niwaju mi" (Esekiẹli 16:50).

Awọn eniyan ki i saba ronu pé wọn n hu iwa ẹṣẹ buburu wọn loju Ọlọrun. Nitootọ, ọpọ eniyan ni n gbiyanju lati fi ẹṣẹ wọn ti o ri ni lara ju pamọ fun awọn ọrẹ wọn. Ṣugbọn Ọlọrun n ri gbogbo wọn. "Ko si ohun ti a bò, ti a kì yio si fihàn; tabi ti o pamọ, ti a ki yio mọ̀" (Luku 12:2). "Nitoripe Ọlọrun yio mu olukuluku iṣẹ wa sinu idajọ, ati olukuluku ohun ìkọkọ, ibã ṣe rere, ibã ṣe buburu" (Oniwasu 12:14).

**Aanu Ọlọrun**

Nigba ti Ọlọrun ri iwa buburu Sodomu on Gomorra, O pinnu lati pa wọn run. Ṣugbọn ṣaaju, O sọ fun Abrahamu ọrẹ Rẹ̀ nipa rẹ. Ọmọ arakunrin Abrahamu, Lọti n gbe ibẹ, nitori naa ni Abrahamu fi ni iwuwo nla lọkan nipa ọran ilu wọnyii.

Lọti wa ni Sodomu nipa yiyan ti ara rẹ̀, lẹyin ti o ti yan pẹtẹlẹ Jọrdani ti o ni omi pupọ, ti o si ti fi oke olokuta silẹ fun arakunrin baba rẹ ti o jẹ agba fun un. Ṣugbọn sibẹ Abrahamu fẹran rẹ, o si gbadura si Ọlọrun lati da ilu naa si nitori ti awọn olododo. Ọlọrun yoo ha da ilu naa si nitori aadọta olododo nibẹ? Ọlọrun dahun: "Bi mo ba ri ãdọta olododo ninu ilu Sodomu njẹ emi o dá gbogbo ibẹ̀ si nitori wọn." Ṣugbọn nigba naa ni Abrahamu bẹru pe wọn le ṣai pọ to bẹẹ. Ọlọrun yoo ha da a si nitori ogoji tabi nitori ọgbọ̀n ani tabi nitori mẹwaa? Bẹẹ ni, Ọlọrun leri lati da ilu naa si nitori ti olododo mẹwaa. Ṣugbọn ko si mẹwaa.

**Ibẹwo Awọn Angẹli**

Awọn angẹli meji wa si ilu Sodomu lati bẹ Lọti wo, ṣugbọn wọn wá ni iri eniyan, Lọti ko si mọ pe angẹli ni wọn. O jokoo ni ẹnu bode ilu naa nibi ti o dabi ẹni pe o n gbiyanju lati ṣe idajọ ododo fun awọn eniyan buburu laaarin awọn ti o n gbe. Peteru Apọsteli sọ fun ni pe ọkan rẹ bajẹ nitori iwa wọbia ati iwa buburu awọn ẹlẹṣẹ laaarin awọn ẹni ti o n gbe. Lai ṣe aniani o gbiyanju lati di òpó iwa mimọ mu laaarin wọn, ṣugbon wọn kọ̀ lati gbọ́ ti rẹ.

Nigba ti Lọti ri i ti awọn angẹli naa wọ ilu, o ba buruburu niwaju wọn. O ri i pe wọn jẹ ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ti ẹṣẹ Sodomu ko si sọ di ẹni ibajẹ. O pe wọn lati wọ si ile rẹ, o fi gbogbo nnkan alejo ti o ni rọ̀ wọn. Awọn angẹli naa kọ́kọ́ fi iwa ọmọluwabi kọ̀; ṣugbọn nigba ti Lọti tẹnumọ ọn, wọn si ba a lọ lati wọ̀ ni gbogbo oru naa.

Ẹni ti o kọ iwe Heberu sọ fun awọn Onigbagbọ́ Heberu pe: “Ẹ máṣe gbagbé lati mã ṣe alejò: nitoripe nipa bẽ li awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli li alejò laimọ̀” (Heberu 13:2). Bi ti Lọti ti ri ni yii. Oun ko mọ̀, nigba ti o pe awọn ọkunrin wọnyii si ile rẹ̀, pe awọn ni angẹli Ọlọrun ti wọn ti wa lati mu un jade kuro ninu ilu naa ki a to pa a run.

Nigba ti awọn eniyan buburu ilu naa ri i pe Lọti n tọju awọn ẹni rere wọnyii, wọn fẹ ṣe wọn nibi. Wọn kigbe tantan ni ẹnu-ọna ile Lọti, wọn tẹnumọ ọn pe awọn ọkunrin naa ni lati bọ sode. Ṣugbọn awọn angẹli naa fa Lọti pada sinu ile, wọn si bu ifọju lu gbogbo awọn eniyan ibi naa, kekere ati nla, ọlọrọ ati talaka, agba ati ewe, ki wọn̄ ma ba le ri ẹnu ọna. O dabi ẹni pe olukuluku ẹlẹgbẹjẹgbẹ eniyan ti o wa ni Sodomu ni o buru gidigidi – kekere ati nla, ọlọrọ ati talaka, agba ati ewe. Dajudaju idajọ tọ si won.

**Wọn ko Naani Ikilọ**

Awọn angẹli naa ran Lọti si ile awọn ọmọbinrin rẹ ti wọn ti gbeyawo lati kilọ fun wọn pe idajọ n bọ ati pe ki wọn sa asala fun ẹmi wọn. “Ṣugbọn o dabi ẹlẹtàn loju awọn ana rẹ̀.”

Idajọ yoo wa sori aye lọjọ kan lai pẹ, awọn Onigbagbọ ododo loni n gbiyanju lati kilọ fun awọn eniyan lati sa kuro ninu ẹṣẹ, ki wọn si ri aabo ninu Ẹjẹ Jesu. Ẹnikẹni ni o le bọ lọwọ idajọ bi oun yoo ba ronupiwada ẹṣẹ rẹ ki o si wi pe ki Jesu dariji oun.

Ṣugbọn fun ọgọọrọ eniyan -- ikilọ nipa idajọ ti n bọ ri bi o ti ri si awọn eniyan Sodomu, itan aṣiwere. Wọn n wi pe, “Nibo ni ileri wíwa rẹ̀ gbé wà? Lati igbati awọn baba ti sùn, ohun gbogbo nlọ bi nwọn̄ ti wà rí lati ìgba ọjọ̀ ìwa” (2 Peteru 3:4). Ṣugbọn Peteru sọ fun ni pe Ọlọrun ko fi ileri Rẹ̀ jafara, Ọrọ Rẹ̀ yoo si ṣẹ. “Ọjọ Oluwa mbọ̀wá bi olè li oru; ninu eyi ti awọn ọrun yio kọja lọ ti awọn ti ariwo nla, ati awọn imọlẹ oju Ọrun yio si ti inu oru gbigbona gidigidi di yíyọ, aiye ati awọn iṣẹ ti o wà ninu rẹ̀ yio si jóna lulu” (2 Peteru 3:9, 10).

Awọn ana Lọti, ti wọn ro pe o n tan wọn ni, duro ninu ilu pẹlu awọn aya wọn, wọn si jona luuluu.

**Owurọ Didan**

Nigba ti ilẹ mọ, awọn angẹli naa le Lọti ni ere, wi pe, “Dide, mu aya rẹ, ati awọn ọmọbinrin rẹ mejeji ti o wà nihin: ki iwọ ki o má ba run ninu ìya ẹ̀ṣẹ̀ ilu yii.” Sibẹ o dabi ẹni pe oju ko kán Lọti rara lati jade, oun ko i ti i ri ki a rọjo ina ati sulfuru lati Ọrun wá ri; ki ni ṣe ti yoo fi maa tara nisisiyii? Ṣugbọn iparun n bọ̀, bi awọn angẹli ko ba ti di ọwọ rẹ̀ mu, ki wọn si ti fa a jade, oun i ba ti parun pẹlu awọn eniyan buburu. Aanu Ọlọrun nikan ni o mu un sala pẹlu ẹmi rẹ̀.

A ba le ṣi ọkan wa paya si ikilọ Ọrọ Ọlọrun! Ọrọ Ọlọrun daju, nigbakugba ni Oluwa si le pe awọn wọnni ti n wọna fun bibọ Rẹ̀ lọ si ile. A ba le fi igba gbogbo ṣọna ki a si maa reti bibọ Rẹ̀, ki a ma ba fi wa silẹ lati kọja ninu Ipọnju Nla!

Awọn angẹli naa wi fun Lọti lati sa asala lọ si ori oke ki o si lọ jinna kuro ni agbegbe iparun naa, ṣugbọn Lọti n fẹ lati lọ si ilu kekere kan ti a n pe ni Soari. Lẹẹkan si i awọn angẹli naa tun ṣaanu fun un, wọn si jẹki o ṣe ifẹ rẹ̀.

Nigba ti Lọti de Soari, oorun ti goke, ọjọ si dabi eyi ti o n dan. Ko si ikuuku lati ba ni lẹru, tabi iṣuju kan ti o ṣajeji. Ko si apẹẹrẹ pe ibi n bọ̀. O dabi ọjọ miiran ṣaa. Ṣugbọn lojiji ojo bẹrẹ si i rọ̀ sori Sodomu on Gomorra – ki i si i ṣe omi. Ina ati sulfuru n dà ṣẹ̀ṣẹ̀ ninu ikuuku eefin, awọn ilu naa pẹlu awọn olugbe inu wọn, pẹlu gbogbo eweko si parun. Kò si nnkan ti o ku laaye. Awọn eniyan gbagbọ́ pe Oku Okun ni o bo ilẹ ti awọn ilu wọnni ti duro si ri, ko si si ẹdá alaaye kankan rara ninu okun naa ri. Ko si atunṣe fun idajọ Ọlọrun lori Sodomu on Gomorra.

**Ọwọ̀n Iyọ**

Awọn angẹli ti kilọ fun Lọti ati awọn ara ile rẹ pe ki wọn̄ ma ṣe boju wo ẹyin, ṣugbọn aya Lọti ko gbọran. Pupọ ninu awọn eniyan buburu wọnni ni i ṣe ọrẹ rẹ̀. Boya oun naa n ronu nipa awọn ọmọ rẹ alaigbọran ti wọn ti fi sẹyin. Nitori naa o boju wo ẹyin, o si di ọwọ̀n iyọ. A royin itan naa ni ọpọlọpọ ọdun lẹyin naa; nigba ti a n royin rẹ, ọwọ̀n naa wà nibẹ sibẹ, o n ran ni leti idajọ lori awọn alaigbọran.

Idajọ ti o tobi ju eyi ti o wa sori Sodomu on Gomorra n bọ wa sori awọn eniyan ti wọn kọ ẹkọ Jesu. Jesu sọ wi pe i ba ṣe pe awọn ilu wọnni ri iṣẹ agbara ti Oun ṣe ni Kapernaumu, wọn i ba ti ronupiwada, a ki ba si ti pa wọn run. Bi Ọlọrun ba pa awọn eniyan buburu wọnni run ti kò gbọ iwaasu Jesu, wo bi idajọ ti o tọ́ ju bẹẹ lọ yoo ti wa sori awọn ti wọn gbọ ọ ti wọn si kọ̀ lati bikita? Lonii gbogbo wa ni anfaani wa fun lati

gbọ iwaasu Jesu. A ba le gbọran ki a si mu ki igbesi-aye wa ba Ọrọ Rẹ̀ mu, ki a si bọ lọwọ gbogbo idajọ ti Ọlọrun yoo da sori awọn ti o kọ Kristi silẹ. Yoo pe awọn eniyan Rẹ̀ wa Ile, bori gbogbo ipọnju ati irora ti yoo wá sori aye ti o ti di arugbo yii.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ṣe ti a o fi pa Sodomu run?

2 Ta ni n gbe ni Sodomu? Bawo ni o ṣe ba Abrahamu tan?

3 Ki ni adura Abrahamu si Ọlọrun nigba ti o gbọ pe a o pa ilu naa run?

4 Bawo ni Lọti ti ṣe si awọn angẹli ti o wá si Sodomu?

5 Ki ni Paulu Apọsteli sọ fun ni nipa alejo ṣiṣe?

6 Bawo ni awọn ana Lọti ṣe gba ikilọ idajọ?

7 Ki ni ṣẹlẹ si wọn?

8 Ki ni ṣẹlẹ si aya Lọti?

9 Bawo ni oju ọjọ ti ri nigba ti idajọ de?

10 K ni idajọ Sodomu on Gomorra?